a ma baa ṣe inunibini si wọn nitori agbelebu Kristi. (Matt 23:27,28; A.A. 15:1; Gal 5:11.)

13. Nitori awọn ti a kọ nila paapaa kò pa òfin mọ́, ṣugbọn wọn nfẹ mu yin kọlà, ki wọn lè maa ṣogo ninu ara yin. (Rom 2:25; Filp 3:3.)

14. Ṣugbọn ki a máṣe rii pe emi nṣogo, bikoṣe ninu agbelebu Jesu Kristi Oluwa wa, nipasẹ ẹni ti a ti kan ayé mọ́ agbelebu fun mi, ati emi fun ayé. (Gal 2:20; Rom 6:2,6.)

15. Nitori pe ninu Kristi Jesu Ikọla kò jẹ ohun kan, tabi aikọla, bikoṣe ẹ̀dá tuntun. (2 Kor 5:17.)

16. Ki alaafia ati aanu wà lori gbogbo awọn ti nrin ni ìlànà yii, ati lori Israẹli Ọlọrun.

17. Lati isinsinyìí lọ, ki ẹnikẹni máṣe yọ mi lẹnu mọ́; nitori emi nru àpá Jesu Oluwa kiri ni ara mi. (2 Kor 1:5.)

**Oore-ọfẹ.**

18. Ará, oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wà pẹlu ẹ̀mí yin. Amin.

49

# AWỌN ARA EFESU

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini Paulu.**

PAULU, Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ Ọlọrun, si awọn ènìyàn-mímọ́ ti o wà ni Efesu, ati si awọn onigbagbọ ninu Kristi Jesu: (2 Kor 1:1; 1 Kor 1:1; Kol 1:1,2; Filp 1:1.)

2. Oore-ọfẹ si yin, ati alaafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba wa ati Kristi Oluwa. (Rom 1:7.)

**Ipilẹṣẹ ijọ Ọlọrun ni Efesu.**

3. Olùbùkún ni Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹni ti o ti fi gbogbo ìbùkún ẹmi ninu awọn ọ̀run bùkún wa ninu Kristi: (2 Kor 1:3; Ef 2:6; 3:10; 6:12.)

4. Ani gẹgẹ bi o ti yàn wa ninu rẹ̀ ṣaaju ipilẹṣẹ ayé, ki awa lè jẹ́ mimọ ati alailabuku niwaju rẹ ninu ifẹ: (Ef 5:27; Kol 1:22; Ef 4:2,15,16.)

5. Ẹni ti o ti yàn wa tẹlẹ si ìsọdọmọ nipa Jesu Kristi fun ara rẹ̀, gẹgẹ bi ìdùnnú ifẹ rẹ̀: (Rom 8:29.)

6. Fun ìyìn ogo oore-ọfẹ rẹ̀, eyi tí ò dà lù wá ninu Àyànfẹ́:

7. Ninu ẹni ti awa ni ìràpadà wa nipa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ wa, gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ oore-ọfẹ rẹ̀: (Kol 1:14.)

8. Eyi ti o sọ di pupọ fun wa ninu gbogbo ọgbọ́n ati òye, (Rom 16:25.)

9. Ẹni ti o ti sọ ohun ijinlẹ ifẹ rẹ̀ di mímọ̀ fun wa, gẹgẹ bi ìdùnnú rẹ̀, eyi ti o ti pinnu ninu rẹ̀,

10. Fun iṣẹ́ ìríjú ti kíkún akókò naa, ki o lè kó ohun gbogbo jọ ninu Kristi, ìbáà ṣe eyi ti nbẹ ninu awọn ọrun, tabi eyi ti nbẹ ni ayé, ani ninu rẹ̀; (Gal 4:4.)

11. Ninu ẹni ti awa ti ri ogún gbà pẹlu, ti a ti pinnu tẹ́lẹ̀ gẹgẹ bi ìmọ̀ ìfẹ́ ẹni naa ti nṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi ìmọ̀ ìfẹ́ rẹ̀. (Ef 3:11; Rom 9:17; Heb 6:17.)

12. Ki awa le jẹ fun ìyìn ogo rẹ̀, awa ti a ti ni ireti ṣaaju ninu Kristi; (ẹsẹ 6,14. Kol 1:16,20.)

13. Ninu ẹni ti ẹyin pẹlu, nigba ti ẹyin ti gbọ́ ọ̀rọ̀ otitọ ihinrere ìgbàlà yin, ninu ẹni ti ẹyin ti gbagbọ pẹlu, a fi Ẹmi Mimọ ileri ṣe èdìdí yin, (Kol 1:5; Ef 4:30.)

14. Eyi ti i ṣe ẹ̀rí ìní wa, fun irapada ohun ini Ọlọrun si ìyìn ogo rẹ̀. (2 Kor 1:22; A.A. 20:32.)

**Adura fun awọn ara Efesu.**

15. Nitori èyí, pẹlu, nigba ti mo ti gburo ìgbàgbọ́ ti nbẹ laarin yin ninu Jesu Oluwa, ati ifẹ yin si gbogbo awọn eniyan mimọ. (Kol 1:4; Ef 3:18.)

16. Emi kò si sinmi lati maa dupẹ nitori yin, ati lati maa dárukọ yin ninu adura mi; (Rom 1:8,9; Kol 1:3,9.)
17. Pe, ki Ọlọrun Jesu Kristi Oluwa wa, Baba ogo, lè fun yin ni Ẹmí nipa ti ọgbọn ati ti ifihan ninu ìmọ̀ rẹ̀: (Isa 57:19; Psm 148:14.)
18. Ki ojú ọkan yin lè mọ́lẹ̀; ki ẹyin lè mọ ohun ti ireti ìpè rẹ̀ jẹ́, ati ohun ti ọ̀rọ̀ ògo ogún rẹ̀ ninu awọn eniyan mímọ́ jẹ́, (Ef 3:12; 1 Kor 12:12; Kol 1:12.)
19. Ati agbara rẹ̀ ti o tobi julọ si awa ti o gbagbọ, gẹgẹ bi iṣẹ agbara rẹ̀, (Filp 3:20; Gal 6:10.)
20. Eyi ti o ṣiṣẹ ninu Kristi, nigba ti o ti ji dide kuro ninu òkú, ti o sì mu un joko lọwọ ọ̀tún ninu awọn ọ̀run, (Matt 16:18; Ifh 21:14.)
21. Ga ju gbogbo ijọba ati ọlá, agbara, ati oyè ati gbogbo orukọ ti a ndá, ki i ṣe ni ayé yìí nikan, ṣugbọn ni èyí ti nbọ̀ pẹlu. (1 Kor 3:16,17.)
22. O si ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ̀ rẹ̀, o si fi i ṣe orí lori ohun gbogbo fun ijọ.
23. Eyi ti i ṣe ara rẹ̀, ẹ̀kún ẹni ti o kún gbogbo ninu ohun gbogbo.

ORI 2.

**Kíkọ́ Ijọ Ọlọrun.**

EYIN ni o si ti sọ di àyè, nigba ti ẹyin ti kú nitori irekọja ati ẹ̀ṣẹ̀ yin, (ẹsẹ 5; Jhn 5:24.)
2. Ninu eyi ti ẹ̀yin ti rìn gẹgẹ bi ipa ti ayé yìí, gẹgẹ bi aláṣẹ agbara ojú ọ̀run, ẹ̀mí ti nṣiṣẹ ni isinsinyìí ninu awọn ọmọ alaigbọran: (Kol 1:25; 1 Tim 1:4.)
3. Ninu awọn ẹni ti gbogbo wa pẹlu ti wà ri ninu ifẹkufẹ ara wa, a nmu ìfẹ́ ara ati ti inú ṣẹ; ati nipa ẹ̀dá awa si ti jẹ ọmọ ibinu, gẹgẹ bi awọn iyoku pẹlu. (A.A. 22:17; Gal 1:12; Rom 16:25.)
4. Ṣugbọn Ọlọrun, ẹni ti i ṣe ọlọ́rọ̀ ni aanu, nitori ifẹ nla rẹ̀ ti o fi fẹ́ wa, (Rom 10:12.)
5. Nigba ti awa tilẹ̀ ti kú nitori irekọja wa, o sọ wá di ààyè pẹlu Kristi (oore-ọfẹ ni a ti fi gbà yín là). (ẹsẹ 1,8.)
6. O sì ti ji wa dide pẹlu rẹ̀, o si ti mú wa joko pẹlu ninu awọn ọrun ninu Kristi Jesu: (Ef 1:20.)
7. Pé ni gbogbo ìgbà ti nbọ ki o baa lè fi ọrọ̀ oore-ọfẹ rẹ̀ ti o pọ rekọja han ninu iṣeun rẹ̀ si wa ninu Kristi Jesu. (Tit 3:4.)
8. Nitori oore-ọfẹ ni a fi gbà yín là nipa igbagbọ; ati eyiyìí ki i ṣe ti ẹyin tikarayin: ẹbun Ọlọrun ni: (Gal 2:16; ẹsẹ 5.)
9. Ki i ṣe nipa iṣẹ́, ki ẹnikẹni ma baa ṣogo. (Rom 3:20,28; 2 Tim 1:9.)
10. Nitori awa ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀ ti a ti dá ninu Kristi Jesu fun iṣẹ rere, ti Ọlọrun ti pèsè tẹ́lẹ̀, ki awa lè maa rìn ninu wọn. (Ef 4:24; Tit 2:14.)
11. Nitori naa ẹ ranti pe, nigbà atijọ rí, ẹyin ti ẹ ti jẹ Keferi nipa ti ara, ti awọn ti a npè ni Akọla ti a fi ọwọ́ ṣe ni ara npè ni Alaikọla. (Rom 2:28; Kol 2:11.)
12. Pé ni akókò naa ẹ̀yin wà laini Kristi, ẹ jẹ́ àjèjì sí anfani awọn ọlọ̀tọ̀ Israeli, ati alejo si awọn majẹmu ileri naa, laini ìrètí, ati laini Ọlọrun ni ayé: (1 Tess 4:5; Gal 4:8.)
13. Ṣugbọn nisinsinyìí ninu Kristi Jesu ẹyin ti o ti jina réré nigba atijọ ri ni a mu sunmọ tosi, nipa ẹjẹ Kristi. (A.A. 2:39; Kol 1:20;Jhn 10:16.)
14. Nitori oun ni alaafia wa, ẹni ti o ti ṣe mejeeji ni ọ̀kan, ti o sì ti wó ogiri ìkelé ti nbẹ laarin; (1 Kor 12:13; Kol 3:15.)
15. Nipa pípa aṣẹ awọn ofin ati ilanà gbogbo rẹ́ ninu ara rẹ̀; ki o lè fi awọn mejeji da ẹni titun kan ninu ara rẹ̀, ki o si ṣe ìlàjà, (Gal 6:15; Kol 1:21,22.)
16. Ati ki o lè mu awọn mejeeji bá Ọlọrun làjà ninu ara kan nipa agbelebu; o si ti pa ìṣọ̀tá naa run nipa rẹ̀: (Kol 1:20,22.)
17. O si ti wá, o si ti waasu alaafia fun ẹyin ti o jinna réré, ati fun awọn ti o sunnmọ tòsí: (Psm 148:14; Isa 57:19.)
18. Nitori nipa rẹ̀ ni awa mejeeji ti ni

ọ̀nà nipa Ẹ̀mí kan sọdọ Baba. (Ef
3:12; 1 Kor 12:13; Kol 1:12.)
19. Njẹ nitori naa ẹ̀yin ki i ṣe ale-
jò ati àtìpó mó, ṣugbọn àjùmọ̀-jẹ́
ọmọ-ìbílẹ̀ pẹlu awọn eniyan-mímọ́, ati
awọn ara ile Ọlọrun; (Filp 3:20; Gal
6:10.)
20. A sì ngbe yín ró lori ìpìlẹ̀ awọn
aposteli, ati awọn woli, Jesu Kristi ti-
kararẹ jẹ́ gẹgẹ bi pataki okuta igun ilé;
(Matt 16:18; Ifh 21:14.)
21. Ninu ẹni ti gbogbo ile naa, ti a
nkọ ṣọkan pọ̀ ti o si ndàgbà sókè si
tẹmpili mimọ kan ninu Oluwa: (1 Kor
3:16,17.)
22. Ninu ẹni ti a ngbe yin ró pọ̀ pẹlu
fun ibujokòó Ọlọrun ninu Ẹmi.

ORI 3.

**Agbara ti Ijọ Ọlọrun ní.**

NITORI eyi, emi paulu, òndè Jesu
Kristi nitori ẹyin Keferi, (A.A.
23:18; Ef 4:1.)
2. Bi ẹ̀yín bá tilẹ ti gbọ ti iṣẹ iriju
oore-ọfẹ Ọlọrun, ti a fifun mi fun yin;
(Kol 1:25; 1 Tim 1:4.)
3. Bi o ti ṣe pe nipa ifihàn ni o ti fi
ohun ijinlẹ hàn fun mi gẹgẹ bi mo ti kọ
ṣaaju ni ọ̀rọ̀ díẹ̀, (A.A. 22:17; Rom
16:25; Gal 1:12.)
4. Nigba ti ẹyin bá kà á, nipa èyí ti
ẹ̀yin o fi lè mọ òye mi ninu ijinlẹ Kri-
sti. (1 Kor 4:1.)
5. Eyi ti a koi tíí fihan awọn ọmọ
eniyan rí ninu ìran miran gbogbo, bi a
ti fi wọn hàn nisinsinyìí fun awọn
aposteli rẹ̀ mimọ ati awọn woli nipa
Ẹmí; (Rom 16:26;3:1;2 Pet3:2.)
6. Pé, awọn Keferi jẹ ajumọjogun
ati ẹ̀yà-ara kannaa, ati alábápín ileri
ninu Kristi Jesu nipa ihinrere; (Gal
3:29; Ef 2:15,16.)
7. Iranṣẹ èyí ti a fi mi ṣe gẹ́gẹ́ bi
ẹ̀bùn oore-ọfẹ Ọlọrun ti a fifun mi,
gẹgẹ bi iṣẹ́ agbara rẹ̀.
8. Fun emi ti o kere jùlọ ninu
gbogbo awọn eniyan mímọ́, ni a fi
oore-ọfẹ yìí fún, lati wàásù àwámárídi
ọ̀rọ̀ Kristi fun awọn Keferi; (1 Kor
15:9; Gal 1:16; Kol 1:27.)
9. Ati lati mu ki gbogbo eniyan rí
kínni iṣẹ́-iriju ohun ìjìnlẹ̀ naa jásí, eyi
ti a ti fi pamọ lati ayébáyé ninu
Ọlọrun, ẹni ti o dá ohun gbogbo nipa
Jesu Kristi: (Kol 1:26,27.)
10. Ki a baa lè fi ọpọlọpọ oniruuru
ọgbọ́n Ọlọrun hàn nisinsinyìí fun awọn
ijoye ati awọn alagbara ninu awọn
ọ̀run, nipasẹ ìjọ, (1 Kor 2:7; Ef 1:21;
1 Pet 1:12.)
11. Gẹgẹ bi ipinnu àtayébáyé ti o ti
pinnu ninu Kristi Jesu Oluwa wa:
12. Ninu ẹni ti awa ni igboya, ati
ọ̀nà pẹlu igbẹkẹle nipa igbagbọ wa
ninu rẹ̀. (Heb 4:16; Ef 2:18.)
13. Nitori naa mo bẹ̀ yin ki aarẹ
maṣe mu yin ni gbogbo wahala mi ni-
tori yin, ti i ṣe ogo yin. (2 Kor 4:1.)
14. Nitori ìdí èyí ni mo ṣe nfi eekún
mi kunlẹ fun Baba Oluwa wa Jesu Kri-
sti. (Filp 2:10.)
15. Orukọ ẹni ti a fi npe gbogbo
idile ti nbẹ ni ọrun ati ni ayé,
16. Ki oun baa lè fifun yin, gẹgẹ bi
ogo rẹ̀, ki a lè fi agbara rẹ̀ mu yin lo-
kun nipa Ẹmí rẹ̀ ninu eniyan-ti-inú.
(Rom 7:22; Kol 1:11; Ef 1:18.)
17. Ki Kristi lè maa gbe inu ọkàn
yín nipa igbagbọ; pé bi ẹ ti nfi
gbòngbò múlẹ̀ ti ẹ si nfi ẹsẹ̀ múlẹ̀ ninu
ifẹ; (Jh 14:23; Kol 1:23.)
18. Ki ẹ̀yín lè ni agbara lati mọ̀ pẹlu
gbogbo awọn eniyan-mimọ, kinni ìbú,
ati gígùn, ati jíjìn, ati gíga naa jẹ́, (Job
11:8,9; Ef 1:18.)
19. Ati lati mọ̀ ifẹ Kristi ti o ta ìmọ̀
yọ, ki a lè fi gbogbo ẹ̀kún Ọlọrun kún
yin, (Kol 2:10; Ef 1:23.)
20. Njẹ ẹni ti o lè ṣe lọpọlọpọ ju
gbogbo èyí ti a nbèèrè tabi ti a nrò lọ,
gẹ́gẹ́ bi agbara ti nṣiṣẹ ninu wa, (Rom
16:25.)
21. Oun ni ki a maa fi ògo fun ninu
ìjọ ati ninu Kristi Jesu títí irandiran
gbogbo, ayé ainipẹkun. (Amin.) (Rom
11:36.)

ORI 4.

**Ìṣọ̀kan Ijọ Ọlọrun.**

NITORI naa emi òndè ninu Oluwa nbẹ yin pé, ki ẹyin maa rìn bi o ti yẹ fun ìpè naa ti a fi pe yin, (Ef 3:1; Kol 1:10.)

2. Pẹlu ìrẹ̀lẹ̀ gbogbo ati inú tútù, pẹlu ipamọra, ẹ maa fi ifẹ farada fun ẹnikeji yin; (Kol 3:12; Ef 1:4.)

3. Ki ẹ si maa làkàkà lati pa iṣọkan Ẹmí mọ́ ni ìdìpọ̀ alaafia. (Kol 3:14.)

4. Ara kan ni nbẹ, ati Ẹmí kan, àní bi a ti pè yin sinu ìrèti kan ti ìpè yín (Kol 3:14.)

5. Oluwa kan, igbagbọ kan, baptismu kan,

6. Ọlọrun kan ati Baba gbogbo, ẹni ti o wà lori gbogbo ati nípá gbogbo ati ninu yin gbogbo. (Rom 11:36.)

7. Ṣugbọn olukuluku wa ni a fi oore-ọ̀fẹ́ fun gẹgẹ bi òṣùwọ̀n ẹ̀bùn Kristi (Rom 12:3.)

8. Nitori naa a wí pé, "Nigba ti ó goke lọ sí ibi giga, o di ìgbèkun ni ìgbèkùn, o si fi ẹ̀bùn fun eniyan (Psm 68:18; Ondj 5:12; Kol 2:15.)

9. (Njẹ niti pe "O goke lọ", Kinni o jẹ́, bikoṣe pe o kọ́ sọkalẹ pẹlu lọ si ìhà isalẹ ilẹ̀? (Jhn 3:13.)

10. Ẹni ti o ti sọkalẹ, oun kannaa ni o si ti gòkè rekọja gbogbo awọn ọ̀run, ki o lè kun ohun gbogbo.)

11. O si ti fi àwọn kan funni bi aposteli; ati àwọn miran bi woli; ati àwọn miran bi ẹfangelisti, ati awọn miran bi oluṣọ-agutan ati olukọni; (1 Kor 12:28.)

12. Fun àṣepé awọn eniyan-mimọ fun iṣẹ́-iranṣẹ, fun ìmúdàgbà ara Kristi; (1 Kor 12:27; 2 Kor 13:9; Ef 1:23.)

13. Títí gbogbo wa yoo fi de ìṣọ̀kan igbagbọ ati ìmọ̀ ọmọ Ọlọrun, titi a o fi di ọkunrin, titi a o fi dé ìwọ̀n gígùn ẹ̀kún Kristi. (1 Kor 14:20; Kol 2:2; Kol 1:28.)

14. Ki awa má ṣe jẹ́ èwe mọ́, ti a nfi gbogbo afẹfẹ ẹ̀kọ́ tì siwa tì sẹ́hìn, ti a si fi ngbá kiri, nipa itanjẹ eniyan, nipa arékérekè fun ọgbọ́nkọ́gbọ́n ati mu ni ṣìnà; (1 Kor 14:20; Ef 6:11; Jms 1:6.)

15. Ṣugbọn ki a maa sọ otitọ ni ìfẹ́, ki a lè maa dàgbàsókè ninu rẹ̀ ni ohun gbogbo, ẹni ti i ṣe orí, ani Kristi: (2 Kor 4:2; Ef 1:22; Kol 1:18.)

16. Lati ọdọ ẹni ti ara naa, ti a nso ṣọ̀kan pọ̀, ti o si nfi ara mọra, nipasẹ̀ oríkèé kọ̀ọ̀kan ti a ti pèsè, nigba ti ẹ̀yà kọọkan bá nṣiṣẹ́ daradara, yoo mu ara dàgbà, yoo si gbé ara oun tikararẹ̀ dide ninu ifẹ.

**Ẹ gbe ọkunrin titun wọ̀.**

17. Njẹ eyi ni mo nwi, ti mo si njẹri ninu Oluwa pé, lati isinsinyií lọ ki ẹ̀yin má ṣe rìn mọ́, ani gẹgẹ bi awọn Keferi ti nrìn ninu ìronú asán wọn, (Rom 1:21; Kol 3:7; 1 Pet 4:3.)

18. Òye awọn ẹni ti o ṣokùnkùn, awọn ti o sì ti di àjèjì si iwa-bi-Ọlọrun nitori àìmọ̀ ti nbẹ ninu wọn, nitori líle ọkàn wọn: (2 Kor 3:14; Ef 2:1,12.)

19. Awọn ẹni ti ọkàn wọn le rekọja, ti wọn si ti fi ara wọn fun wọbia, lati maa fi iwọra ṣiṣẹ ìwà-eeri gbogbo. (Rom 1:24; Kol 3:5; 1 Tim 4:2.)

20. Ṣugbọn a kò fi Kristi kọ yin bẹ́ẹ̀

21. Bi o ba ṣe pe nitootọ ni ẹ ti gbohun rẹ̀ ti a sì ti kọ́ yin ninu rẹ̀, gẹgẹ bi otitọ ti nbẹ ninu Jesu:

22. Pé, niti ìwà yin atijọ, ki ẹyin bọ́ ogbologbo ọkunrin nì silẹ, eyi to o díbàjẹ́ gẹgẹ bi ìfẹ́kúfẹ́ ẹ̀tàn; (1 Pet 2:1; Rom 6:6,4; 2 Kor 5:17.)

23. Ki ẹ si di titun ni ẹ̀mí inú yín:

24. Ki ẹ si gbe ọkunrin titun wọ̀, eyi ti a dá ni àwòrán Ọlọrun ninu ododo ati ìwà-mimọ ti otitọ. (Kol 3:10.)

25. Nitori naa ẹ fi èké ṣiṣe sílẹ̀, ki olukuluku yin maa ba ọmọnikeji rẹ sọ òtítọ́, nitori ẹ̀yà-ara ọmọnikeji wa ni awa jẹ́. (Esk 8:16; Rom 12:5.)

26. Ẹ binu; ẹ ma si ṣe ṣẹ̀; ẹ ma ṣe jẹ ki òòrùn wọ̀ bá ibinu yín: (Psm 37:8.)

27. Bẹẹ ni ki ẹ má ṣe fi àyè fun Èṣù. (2 Kor 2:10,11.)

28. Ki ẹni ti njalè má ṣe jalè mọ́: ṣugbọn ki o kúkú maa ṣe làálàá, ki o

maa fi ọwọ́ rẹ ṣiṣẹ ohun ti o dara, ki oun lè ní lati pín fun ẹni ti o ṣe alaini. (A.A. 20:35; Luk 3:11.)

29. Ẹ maṣe jẹ ki ọ̀rọ̀ idibajẹ kan ti ẹnu yin jade, ṣugbọn irú eyi ti o dara fun ẹ̀kọ́, ki o lè maa fi oore-ọ̀fẹ́ fun awọn ti ngbọ.

30. Ẹ ma si ṣe mu Ẹmi Mimọ Ọlọrun binu, ẹni ti a fi ṣe edidi yin de ọjọ idande. (Rom 8:23; 1 Tess 5:19.)

31. Gbogbo ìwà kíroró ati ibinu, ati irunu, ati ariwo, ati ọ̀rọ̀ buburu ni ki a mú kuro lọdọ yin, pẹlu gbogbo àránkan: (Kol 3:8; Tit 3:3.)

32. Ẹ maa ṣore fun ọmọnikeji yin, ẹ ni ìyọ́nú, ẹ maa dáríjì ara yin, gẹgẹ bi Ọlọrun ninu Kristi ti darijì yín. (Matt 6:14,15; 2 Kor 2:10.)

ORI 5.

NITORI naa ẹ maa ṣe afarawé Ọlọrun bi awọn ọmọ ọ̀wọ́n; (Luk 6:36.)

2. Ẹ sì maa rìn ni ìfẹ́, gẹgẹ bí Kristi pẹlu ti fẹ́ wa, ti o si fi ara rẹ̀ fun wa ni ọrẹ ati ẹbọ fun Ọlọrun fun òórùn dídùn. (1 Tess 4:9; Gal 1:4; 2 Kor 2:15.)

3. Ṣugbọn àgbèrè ati gbogbo ìwà-èérì, tabi ojúkòkòrò, ki a má tilẹ̀ darukọ rẹ laarin yin mọ́, bi o ti yẹ awọn eniyan-mimọ; (Rom 6:13; 1 Kor 5:1; Kol 3:5.)

4. Ibaa ṣe ìwà ọ̀bùn, ati isọrọ wèrè, tabi ìṣẹ̀fẹ̀ awọn ohun ti kò tọ́; ṣugbọn ẹ kuku maa dupẹ,

5. Nitori ẹ̀yín mọ èyí daju pé, kò sí panṣaga, tabi aláìmọ́ eniyan, tabi olojukokoro, (ti i ṣe abọriṣa), ti yoo ni ìní kan ni ijọba Kristi ati ti Ọlọrun. (1 Kor 6:9; Kol 3:5.)

6. Ẹ má ṣe jẹ́ ki ẹnikeni fi ọ̀rọ̀ asán tàn yin jẹ: nitori nipasẹ̀ nkan wọnyìí ni ibinu Ọlọrun fi nbọ̀ wá sori awọn ọmọ alaigbọran. (Jer 29:8; Rom 1:18.)

7. Nitori naa ẹ má ṣe jẹ alájọpin pẹlu wọn.

8. Nitori ẹyin ti jẹ́ òkùnkùn lẹẹkan, ṣugbọn nisinsinyìí, ẹ̀yin di imọlẹ, nipa ti Oluwa: ẹ maa rin gẹ́gẹ́ bi awọn ọmọ ìmọ́lẹ̀: (Jhn 8:12; Luk 16:8.)

9. (Nitori eso *imọlẹ wà ninu iṣore gbogbo ati ododo ati otitọ́), (Gal 5:22.)

10. Ẹ si maa wadi ohun ti i ṣe itẹwọgba fun Oluwa,

11. Ẹ má sì ba àìléso iṣẹ òkùnkùn kẹgbẹ pọ̀, ṣugbọn ẹ kúkú maa ba wọn wí. (Rom 6:21; 1 Kor 5:9.)

12. Nitori ìtìjú tilẹ ni lati maa sọ̀rọ̀ nkan wọnyìí ti wọn nṣe níkọ̀kọ̀ (Rom 1:24.)

13. Ṣugbọn ohun gbogbo ti a túsíta ni imọlẹ nfi hàn: nitori ohun-kohun ti o ba fi nkan hàn imọlẹ ni.

14. Nitori naa ni o ṣe wi pe, "Jí, ìwọ ẹni ti o sun, si jinde kuro ninu òkú, Kristi yoo si fun ọ ni imọlẹ." (Isa 60:1; Jhn 5:25.)

15. Nitori naa ẹ kiyesi lati maa rin ni ìwà pípé, ki i ṣe bi awọn aláìlọ́gbọ́n, ṣugbọn bi awọn ọlọ́gbọ́n;

16. Ẹ maa ra ìgbà pada, nitori buburu ni awọn ọjọ. (Kol 4:5; Ef 6:13.)

17. Nitori naa ẹ má ṣe jẹ aláìloye, ṣugbọn ẹ maa moye ohun ti ìfẹ́ Oluwa jásí. (Rom 12:2; 1 Tess 4:3.)

18. Ẹ má si ṣe mu waini ni amupara, ninu eyi ti rudurudu wà; ṣugbọn ẹ kún fun Ẹmi; (Owe 20:1; Luk 1:15.)

19. Ẹ si maa bá ara yin sọ̀rọ̀ ninu Psalmu, ati orin ìyìn, ati orin ẹ̀mí, ẹ maa kọrin, ki ẹ si maa kọrin dídùn ni ọkàn yin si Oluwa; (A.A. 16:25; Kol 3:16.)

20. Ẹ maa dupẹ nigba gbogbo fun ohun gbogbo lọwọ Ọlọrun, ani Baba, ni orukọ Jesu Kristi Oluwa wa; (Psm 34:1; Heb 13,15.)

**Idile Onigbagbọ.**

21. Ẹ maa tẹriba fun ara yin ni ibẹru Ọlọrun.

22. Ẹyin aya, ẹ maa tẹriba fun awọn ọkọ yin, gẹgẹ bi fun Oluwa. (Gen 3:16; Ef 6:5.)

(9) *Awọn Bibeli miran pe eyi ni "Ẹmi", ṣugbọn kò rí bẹẹ ninu Bibeli ti èdè Griki. (wo ẹsẹ 13, ati 14.)

23. Nitori pe ọkọ ni nṣe ori aya, gẹgẹ bi Kristi ti ṣe ori ijọ, tii ṣe ara rẹ̀: oun si ni Olugbala rẹ̀. (1 Kor 11:3; Kol 1:18; Ef 1:23.)

24. Nitori naa gẹgẹ bi ijọ ti tẹriba fun Kristi, bẹẹ sì ni ki àwọn aya maa ṣe si ọkọ wọn ni ohun gbogbo. (Kol 3:18.)

25. Ẹyin ọkọ, ẹ fẹran awọn aya yín, gẹgẹ bi Kristi ti fẹran ijọ, ti o si fi ara rẹ̀ fun un, (Kol 3:19.)

26. Ki oun lè sọ ọ di mímọ́ lẹhin ti o ti fi ọ̀rọ̀ wẹ̀ ẹ́ mọ́ ninu agbada omi, (Tit 3:5.)

27. Ki oun le mu un wá sọdọ ara rẹ bi ìjọ ti o logo laini àbàwọ́n, tabi àlébù kan, tabi irú nkan bawọnyìí; ṣugbọn ki o lè jẹ mímọ́ ati alaini àbùkù. (Kol 1:22; Ef 1:4.)

28. Bẹẹ ni o tọ́ ki awọn ọkunrin maa fẹran aya wọn gẹgẹ bi ara awọn tikarawọn. (ẹsẹ 25.)

29. Nitori kò si ẹnikan ti o ti korira ara rẹ̀; bikòṣepé ki o maa bọ́ ọ ki o si maa ṣìkẹ́ rẹ̀ gẹgẹ bi Kristi sì ti nṣe sí ijọ.

30. Nitori pé awa ni ẹ̀yà-ara rẹ̀, ati ti ẹran-ara rẹ̀, ati ti egungun ara rẹ̀. (1 Kor 6:15; Ef 1:23.)

31. "Nitori èyí ni ọkunrin yoo ṣe fi baba ati iya rẹ̀ silẹ̀, oun o si dàpọ̀ mọ́ aya rẹ̀, awọn mejeeji a si di ara kan." (Gen 2:24; Matt 19:5; 1 Kor 6:16.)

32. Aṣiri nla ni èyí: ṣugbọn emi nsọ nipa ti Kristi ati ti ijọ. (Kol 3:19; 1 Pet 3:6.)

33. Ṣugbọn ki olukuluku yin fẹran aya rẹ̀ bẹẹ gẹgẹ bi oun tikararẹ̀; ki aya si bẹ̀rù ọkọ rẹ̀.

## ORI 6.

EYIN ọmọ, ẹ maa gbọ ti awọn obi yin ninu Oluwa: nitori pé èyí ni o tọ́. (Kol 3:20.)

2. "Bọwọ fun baba ati ìyá rẹ" (eyi ti i ṣe ofin kinni pẹlu ileri), (Deut 5:16.)

3. "Ki o le dara fun ọ, ati ki iwọ le wà pẹ́ ni ayé."

4. Ati ẹyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ yin binu: ṣugbọn ẹ maa tọ́ wọn ninu ẹkọ ati ikilọ Oluwa. (Gen 18:19; Kol 3:21.)

5. Ẹyin ọmọ-ọdọ, ẹ maa gbọ́ ti awọn oluwa yin nipa ti ara, pẹlu ìbẹ̀rù ati ìwárìrì, ni otitọ ọkan yin, bi ẹni pe si Kristi. (1 Kro 29:17; Kol 3:12; 1 Tim 6:1; Filp 2:12.)

6. Ki i ṣe ti àrí-oju-ṣe bi awọn ti nwu eniyan; ṣugbọn gẹgẹ bi awọn ẹrú Kristi, ẹ maa ṣe ifẹ Ọlọrun lati inu wá.

7. Ẹ maa fi inu rere sìn bí sí Oluwa, kii si ṣe sí eniyan (Kol 3:23.)

8. Bi ẹyin ti mọ̀ pe ohun rere ti olukuluku bá ṣe, oun naa ni yoo si gbà pada lọdọ Oluwa, ibaa ṣe ẹrú, tabi ominira.

9. Ati ẹyin oluwa, ẹ maa ṣe ohun kannaa si wọn, ẹ maa dín ìbẹ̀rù yín kù; bi ẹyin ti mọ̀ pe Oluwa ẹyin tikarayin si nbẹ ni ọ̀run; kò sì sí ojuṣaju eniyan lọ́dọ̀ rẹ̀, (Lef 25:43; Jhn 13:13; Kol 3:25.)

**Ẹ gbé ihamọra Ọlọrun wọ̀.**

10. Lakótán, ara mi, ẹ jẹ alagbara ninu Oluwa, ati ninu agbara ìpá rẹ̀. (1 Kor 6:13; Ef 1:19.)

11. Ẹ gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki ẹyin lè kọ ojú ìjà si arekérekè Èṣù. (1 Kor 16:21.)

12. Nitori pe ki i ṣe èjẹ̀ ati ẹran-ara ni awa nbá jìjàkadì, ṣugbọn awọn ijoye, awọn ọlọ́lá, awọn aláṣẹ ibi òkùnkùn ayé yìí, ati awọn ẹmi buburu ni ojú ọrun. (Rom 8:38; 1 Kor 9:25; 10:4.)

13. Nitori naa ẹ gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki ẹyin lè duro tiiri si ọjọ ibi, nigba ti ẹyin bá sì ti ṣe ohun gbogbo tán, ki ẹ si duro. (2 Kor 10:4; Ef 5:16.)

14. Ẹ duro nitori naa lẹhin ti ẹ ti fi àmùrè otitọ di ẹ̀gbẹ́ yin, ti ẹ si ti di ìgbàyà ododo mọra; (Isa 11:5; 59:17.)

15. Ti ẹ si ti fi imura ihinrere alaafia wọ ẹsẹ yin ni bàtà; (Isa 52:7.)

16. Lékè gbogbo rẹ̀, ẹ mu apata igbagbọ, nipa eyi ti ẹyin lè maa fi paná gbogbo ọfà iná ẹni ibi náà. (1 Jhn 5:4.)

17. Ki ẹ si mu aṣibori ìgbàlà, ati idà Ẹmí, ti i ṣe ọ̀rọ̀ Ọlọrun: (Isa 59:17; Heb 4:12; 1 Tess 5:8.)

18. Pẹlu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ ni ki ẹ maa gbadura nigba gbogbo ninu Ẹmí, ki ẹ si maa ṣọra si i ninu iduroṣinṣin gbogbo, ati ẹ̀bẹ̀ fun gbogbo eniyan-mímọ́: (Matt 26:41; Luk 18:1; Filp 1:4.)

19. Ati fun mi, ki a lè fi ohùn fun mi ki emi lè maa fi ìgbóyà ya ẹnu mi, lati maa fi ohun ijinlẹ ihinrere hàn, (A.A. 4:29; 2 Kor 3:12.)

20. Nitori eyi ti emi jẹ ikọ̀ ninu ẹ̀wọ̀n: ki emi lè maa fi ìgbóyà sọ̀rọ̀ ninu rẹ̀, gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati maa sọ. (2 Kor 5:20; Filp 1:20.)

**Ọ̀rọ̀ asọpari.**

21. Ṣugbọn ki ẹyin pẹlu lè mọ̀ bi nkan ti rí fun mi, bi mo ti nṣe si, Tikiku, arakunrin olufẹ ati iranṣẹ olootọ ninu Oluwa, yoo sọ ohun gbogbo di mímọ̀ fun yin: (A.A. 20:4.)

22. Ẹni ti mo rán si yin nitori èyí naa, ki ẹ lè mọ̀ bi a ti wà, ki oun lè tu ọkàn yín ninu.

23. Alaafia fun awọn ará, ati ifẹ pẹlu igbagbọ, lati ọdọ Ọlọrun Baba wa, ati Oluwa wa Jesu Kristi. (1 Pet 5:14; Gal 5:6.)

24. Ki oore-ọ̀fẹ́ wà pẹlu gbogbo awọn ti o fẹ Oluwa wa Jesu Kristi ni àìṣẹ̀tàn.

50

# AWỌN ARA FILIPPI

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU ati Timoteu, awọn iranṣẹ Jesu Kristi, sí gbogbo awon eniyan-mímọ́ ninu Kristi Jesu ti o wà ni Filippi, pẹlu *awọn biṣọbu ati awọn diakoni: (2 Kor 1:1; A.A. 16:1; 1 Kor 1:2.)

2. Oore-ọ̀fẹ́ si yin, ati alaafia, lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun Baba wá, ati Oluwa Jesu Kristi. (1 Pet. 1:2.)

**Ọpẹ́ ati Adura Fun Ijọ Filippi.**

3. Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi ninu gbogbo iranti yin ti mo nṣe, (1 Kor 1:4.)

4. Nigbagbogbo ninu gbogbo adura mi fun yin ni emi nfi ayọ̀ bẹ̀bẹ̀, (Rom. 1:9.)

5. Nitori ìdàpọ̀ yin ninu ihinrere lati ọjọ kinni wá titi fi di isinsinyìí. (A.A. 2:42; Rom 12:13.)

6. Ohun kan yìí saa dá mi loju pe, ẹni ti o ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere ninu yin, yoo ṣe àṣepé rẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi: (ẹsẹ 10.)

7. Gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati ro eyi nipa gbogbo yin, nitori ti mo fi yin sọ́kàn mi, niwọn bi o ti jẹ pe gbogbo yin ni alábapin oore-ọ̀fẹ́ mi ninu ìdè mi, ati ninu ìdáhùn-ẹjọ mi, ati ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ihinrere. (2Pet1:13; 2Kor7:3; ẹsẹ13-17)

8. Nitori Ọlọrun ni ẹlẹri mi, bi mo ti nṣafẹri yin to gidigidi ninu ìyọ́nú Jesu Kristi. (Rom 1:9; Gal 1:20.)

9. Eyi sì ni mo ngbadura fún pé, ki ìfẹ́ yin lè maa pọ̀ si i siwaju ati siwaju ninu ìmọ̀ ati ìmòye gbogbo. (1 Tess 3:12; Kol 1:9.)

10. Ki ẹyin lè dán ohun ti o dara yàtọ̀ wò; ki ẹ si jasi olododo ati alaijẹ-ohun-ìkọ̀sẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi:

11. Lẹhin ìgbà ti ẹ ti kún fun eso

(1) *Awọn biṣọbu ati awọn diakoni, tumọsi, Awọn alabojuto ati awọn iranṣẹ ti o nran awọn alabojuto lọwọ ninu ijọ; (wo Tit 1:5–9; 1 Tim 3:1–13.)